

ÌWÉ ÀKÓJỌPỌ̀ ÀTÙPÀ OGO

FÚN ÈYÍKÉYÌÍ IDOJUKỌ

LÁTI ỌWỌ

ELHADAADIY KAFAANIY GNF

.
ORO AKOSO
Mo juba akoda aye, mo juba aseda aye, mo juba Olorun ton
be ki aye toma be, mo juba Olorun ti yio si mawa nigbati aye koni simo
Mo juba gbogbo ajunilo
Mo juba gbogbo awon tiwon nbo leyin
Mo se akojopo iwe yi fun iwulo gbogbo eda patapata, yala musulumi, chriteni,tabi elesin abalaye, iwe akojopo atupa ogo eyi ti o fi ara pamo, fun awon eda kan ti o si han si awon edakan gbangba.
Ni sise iwe yi mo juba baba mi oguns Eniti o funmi ni opolopo alaye nipa awon ohun ijinle ti o wa ninu iwe yii
Gbogbo awon ohun ijinle ti awon agba ijohun finse agbara ti
o dabi wipe oti di igbagbe, ni atu jade ninu iwe yi, ki olukuluku ki o gbiyanju kio lo ni tire
Gbogbo awon egbogi inu iwe yi lo daju sakasaka.
Ejowo gbogbo eda ti o ba fe dawole ise inu iwe akojopo atupa ogo yii ejo e je kia se ni mimo, pelu okan kan soso,
Lagbara Olorun ao nise aseti laye
09011908668
09151611472

{ORO DIE LORI AAJO LILO.}

Opo onise owo & Businessman:-- iru ise wo loye ki awon Businessman & onise owo malo, ise won ise connection ni, nitori biwon base moyan to niwon yio se gba ise to Beni ise aye ni opo ise, Oshole togboju, awure eyonu ati Biro agbara Anu, Biro yini won yio malo lati fi ko cotation fun awon customer nitori ero po to submit contrate tiwon

batiri tie bai, kiwon bale feran e.

ALFA, WOLI, BABA ALAWO
Pupo ninu awon iranse meteta yi ni kosi ona abayo fun latara wipe won o mo nkan tio Kan ninu Oro won, elomi aworo towa lenu ona re yio le ni 21, Beni arimole koni onka, hmm nje iwo mo wipe eniti aiye ba nse eniti aiye ndalamu bi iru won lo aworo konije, aimoye won niwon ti fori ko ogun ologun, elomi ninu won Kori alanu, ise tiyin toye kie lo gbajumo ju re *IMULE orisirisi ni Lilo, eyonu ati ebe agba* Beni kie sunmo awon tonimo juyin lo *"tiwonje oninure"*
Elekeji adugbo ti awon eleye baposi, tie ba njo ogun nibe problem ni, elomi inu ile face me and Face you longbe eyinkule loti njo ogun mio ni tan e won ti to(urin)sinu ikoko tio fin jo ogun yen.
Alfa Toba fe se jalabi mio ni paro yio po lasiri yio si jade sita, kuro ni family house yin, logba office sita.
EYIN OLOPA, SOLDIER, SECURITIES, OSISE IJOBA
Tie ba nwa agbega agbega ekoko lo ka iwe si, tie ba ti kawe tan ewa lowa ajo taara Lori bi eyin na sele de ipo giga, nitori elomi o kawe de level to nbere fun emajeki ama tan arawa,
Ajo Lori ki oga yonu si omo ise otoni, aajo Lori ki oga se omo ise lore oto ni, sugbon promotion certificate ati aajo niyio tete gbe e debe nitori elesekan tofe sare lati eko si ibadan ona niyio taku si,
Sora lati ma lo mayehun tabi afose fun customer nitori bi alo balo abo nbo,
Awon ogun Kan wa tole koba ojo iwaju omo, idi niyen tiwon bani baba re lo nse e, iya re lo nse e, olejepe asise ogun tiwon tise nigba ewe lo nse atako fun aseyori tie loni. Mistake ti baba tie se gbiyanju kio correct ara re kuro ninu asise na.
Eyin Alfa woli baba alawo, esora Lori awon ise tie

bafe ma se fun yan, nitori agbalagba to ro efo ika omore yio je, ebire yio je ninu e.

(1)
AROBI
Ewe etiponla, ewe oju oro, ewe alupaida, a o gun mó ose dudu. A o maa fi we ori de orun. A ko gbodo fi we gbogbo ara o.
NB: Ao gbodo fiwe gbogbo ara OLEWU

(2)
AROBI ki enikeni toba sasi ku
A o fa gbogbo irun ori wa tan, A o ko sinu ape ijogun, A o fi odidi Atare kan lelori, A o jo papo, A o fi foko tutu mu lekan soso nbe

(3)
ASETA ASINA
Ewe imi esu oojo teso-teso re, a o jo pelu odidi atare kan, a o lo pelu epo obo, a o wa po lose, a o fi iyo die sinu igba, a o fi igbin to pinu le lori, a o wa ko ose yen le lori, leyin ojo keta, a o ma fi we.
Akiyesi: Ale nikan ni wiwe re

(4)
ASINA ATUDE
Ẹwà èwe lápá lápá Pupa, odindi atare kàn, a ó gùn papọ mo ọ̀sẹ̀dúdú, tí aba gùn tán ao ko si ori kánkán ibile, tí a bati fẹ wẹ nínú baluwe tàbí omi odò tí onsan, ao fi epo pupa pa gbogbo ara láti orí dé ẹsẹ. Bí àtin we ọ̀sẹ̀yi, ao koko

gbàdúrà wí we owó aiye tàbí ìdiwọ̀ kúrò ní ara ati isegun ota, leyin náà ao gba àdúrà kí ona sì, kí ona tódi kò là.
ÀKÍYÈSÍ PATAKI Kankan tí afiwe kò gbọ́dọ̀bá wà délé, ao gbe ilẹ̀
tí a ó sì rí mọ́
lẹ̀
,
pelu gb��lóhùn wípé àti kò ọwọ ota bole, àsiti Segun ọta láti òní lọ. *Isẹ yí dájú

(5)
*GBÓGBÓNÍSÉ ÀWÒGBÀÀRUN

ỌTÍ ÒYÌNBÓ ÀO BÙ ÌYỌ SÍNÚ RẸ ÀO MÁ MÚ NÍ GAASI KÁNKÁN LÓJÚMÒ, GBÓGBÓ ÀRÙN TÍ ÓBA WÁ NÍ INÚ WÁ LÀÓ
YÀ MỌ IGBẸ ÒÒÒ ÀKÍYÈSÍ: ẸJỌ́ TÍ ABÁ NLÒ ISẸ YÌÍ Ẹ MÁ JẸ́KÍ ÀJÍǸNÁ SÌ ILÉ NÍTORÍ YÍÒ YÀWÁ NÍ IGBẸ ÒÒÒ

(6)
ỌSẸ IFERAN
EWÉ BOMBOM 16,EWÉ ỌDÁN IBILẸ
GÍDÍ16,ÌTÀNNÁ AKỌ ÌBẸ̀R
PẸ̀ TÍ KÒ NÍ ÌYÈ ,ÀO WÀ GÙN MẸTẸTA PỌ ,ÀO FÍ ỌSẸ
KÒ ,ÀO KÒ SÍNÚ ÌKÉ FÚNFUN ,ÀO GBÉ PAMO DÍ ỌJỌ KẸTA ,ẸNÌNÁ YÍÒ MÁ FÍ WẸ ANYTIME. TÍ Ò BÁ JẸ OBÌNRIN NÍ Ó ṢÉ
IṢẸ YÍ, ỌJỌ TÓ BÁ TÍ BẸRẸ MENSURATION KÒ MÁ LÓ ÓÒ, NÍTORÍ YÍÒ BÀJÉ.

(7)
ASEJE AWURE
Ewe omisinmisin gogoro, Eyin adie ibile merin.
Sise re: Ao lo ewe yi kunna daada, ao fa sinu abo kan, ao wa jo omi eyin naa sinu isasun ti a

fe lo, ao po ewe ti a lo mo ninu isasun naa, ao fi iyo ati epo pupa si, ao din gege bi ati ndin
eyin je, ti koni jona. Ti o ba jinna tan, ao so sori osuka kan, Ao wa fi iyere-osun te ifa EjiOgbe sinu Opon ifa tabi paper funfun kan (Immaculate white paper), ao pe ofo re si, ao da
sinu Obe naa ti a ba pe ofo re tan.
PIN:
Alapa masise l'oruko ti a npe Ifa 3X
Amona owo mare l'oruko ti a npe Esu odara,
Oloti kii pe esinsin ko to wa mu oti,
Alagbede kii pe agbe kio to wa gbon ada re,
Oso to nbe nile yi, e ma pa ohun mi da,
Aje to nbe nile yi, e ma pa ohun mi da,
Ewe olomumuyeye kii pa ohun Oba Orisa da,
Emi lagbaja omo lagbaja ti di Ewe Olomumuyeye,
Omo araiye e ma se pa ohun mi da,
Ki e fi owo ati ola tun mi se,
Adura lopolopo, leyin re, ao da sinu Obe naa, ao je, ao mu ohun ti o ba wun wa sin.
N.B: Ewe omisinmisin, ni a npe ni Ewe Olomumu yeye ti a ba fe lo.

(8)
ASEJE EBE AWON AGBA
Ao wa eyin ororo 3 ewe orijin ao lo pelu iyere 9, ati ewe mafowokanomomi ao wa fi ori din
tio ba jina ao wa sokale sori osuka ao wa jeni ihoho omoluabi.
Oru ganjo ni ao sa isẹ yìí.

(9)
ASEJE EYONU
Ewe oriji
Ewe ajeobale
A o gun pelu iyere, a o fi se eyin agric merin je lepo niyo
ose re
ewe rerinkomi/ imiesu

epo obo a o gun papo, a o fi ose koo a o ma fi we.

(10)
ASIRI IFA OSO IMULE OWO NLA TODAJU BIIKU

EYE IGUN AAYE KAN,
EYE KOWEE META,
ORI IJAPA 16,
EKU ASIN 16,
OGA GBIGBE 16,
AKO ALAMU 16,
ABO ALAMU 16,
EYE OOBE 16,
OPOLO GBIGBE 16,
EYE ADAN 16,
ALAKAN 16,
ODIDI ATARE 16,
ESURU PUPA TA GESI 16,
ISU OGIRISAKO TÁ GESI 16,
ESO IDO PUPO,
ESO WERENJE PUPO.
……
.. SISE RÉ:- Ao mu eiye igun yii ao pa, ao la aya ré, ao wa gbe sinu osunwon aso pupa ti a ti ran kale, ao wa ko gbogbo eroja oke yen sori igbaaya igun naa ninu apo aso pupa yii, ao wa dii papo pelu osunwon aso pupa naa, ao tun gbe sinu osunwon aso dudu ti, ao dii pa, ao tun gbe sinu osunwon aso funfun, ao gbe sinu ape ijoogun, ao tu igo epo ati adin kookan sori oogun yii ninu agbada, ao tun ju oori amo nla kan si, ao ta epo pupa yika adiro naa, ao jo, ao maa fi ataijosin ko ina ré, toba jotan ao lo kunna daadaa, ao ro sinu agbe kekere tobalegba, ao fi eran obuko kan bo agbe naa, ao fi eran naa se saara fun awon eyan, ao yo ti ipese nibe.

LILO RÉ:- Ao maa fi oti oyinbo gidi lo oogun yii

NB(11)
OBA IMULE TI AWON AGBA O FI NI DI WA LOWO MO LORI ISE TI ANSE TODAJU

Odindi eye olongo 7, ado igbemi 3, atare kan, Ado nla kan.
SISE RE: ao jo gbogbo eroja yi papo, ayafi ado nla yen nikan. Ao lo kuna daada, ao wa ro sinu ado nla yi.

LILO RE:Ao bu die ti a fe loo si atelewo wa osi, ao pe gbolohun re si, ao wa fi omi lasan loo

GBOLOHUN RE
Asabikin, arinbikin ba won se pekipeki,
Adaji jeran oru, ajedo eniyan tutu mabi,
Obe meta ni won fun won lode isaluaye,
Aje fun won lobe ide, orisa fun won lobe oje,
Ogun fun won lobe irin dudu. Ojukokoro ni won fi gba towo ogun lowo ogun.
adedee, abedee logun roko logun reremoja !
ibe lawa ta gbe nmule eleye. Eyin eleye, emi............... eleye. Eleye meji won kii dale arawon. Oso ile, e ma dami , aje ile , e ma dami oo.

(12)

IMULE TI O MA NSINA OWO FUNYAN
Okete Aaye Kan, Ako Fun Okunrin, Abo Fun Obinrin Ologbo Nla Aye Kan, Ako Fun Okunrin, Abo Fun Obinrin, Eye Kowe Dudu Kan Tope Daada, Egbo Tude Idi Pupo, Odidi Atare Nla Kan, Ape Ijogun Tuntun Kan, Ado Seere Kan, Akuko Adie To Gbo Daada Kan.
SISE RE: A o Pa Ologbo Ati Okete Na Ni Ipa Awo, Emi Ma Npa Okun So Fun won Ni. A o Fi Obe Tabi Blade La Inu Awon Mejeeji, A o Ko Ifun Okete

Sinu Ologbo , A o Ko Ifun Ologbo Sinu Okete . A o Fi Owu Dudu Ati FunFun Ran Mejeeji Pada. A o Gbe Mejeeji Sinu Ape Ijogun, A o Koju Ara Won Sira Won Ninu Ape, A o Fi Eye Kowe Si Arin Awon Mejeeji, A o Ko Egbo Tude Le Won Mole Daada, A o Fi Atare Odidi Kan Le Lori. A o De Ape Na, A o Fi Epo Pupa Round Aro Idana, A o Jo Ise Na, A o Lo Kunna Daada, A o Ro Sinu Seere Na, A o Pa Akuko Adie Yen, A o Ro Gbogbo Eje Re Si Ara Seere Na, A o Fi Adie Yen Se Saara Ni, Eni Toni Ise Yi Ko Gbodo Je Ninu Adie Na o. A o Gbe Seere Na Sinu Asuwon Aso FunFun, A o Gbe Ko Sibi To Ba Pamo Daada, Idi Re Ko Gbodo Kanle Mo.
LILO RE: A o Wa Peak Milk Bi Dozen Tabi Half Dozen, A o Tu Sinu Keg Kan, A o Da Igo Oyin Gidi Kan Mo, A o Ji Po Daada, Oun La o Fi Ma Lo Ise Yi Ni Alaale. Eni Ti Koba Le Fi Nkan Yi Lo, E ma Fi Foko Tutu Mu Tabi Fi Hot Lo Ni Alaale.

(13)

ITUWO ATUDE TOGBONA JANJAN

OGUN YI BURU TOBEGE TIWON BANDI ENIYAN LOWO TIWON KOBATUWO ENINA YIO KU, OGUN YIII SI TUN SISE FUN ENITI OGUN O BA KIN SISE LARARE

AYE OPOLO KAN TOGBO EPO OBO
EPO PUPA IGO KAN, IKOKO TUNTUN KAN SISERE AO FI OWO MU OPOLO YII AO SE ADURA SI LETI OTUN AO SEPE FUN AWON OTA WA NI ETI OSI, AO WA FI SIBIKAN, AO DA EPO PUPA YEN SINU IKOKO TUNTUN YEN AO WA GBE KANA TIO GBA DADA AO WA JU EPO OBO SINU REE, TIO BA TI GBO DINDIN EPO OBO YIII AO WA JU OPOLO YEN SINU REE TIO DIN GBE DADA YIO GBE TOBA GBE DADA AO SO KALE AO WA FI NKANKAN YO

OPOLO YIII PELU EPO OBO AO WA LO TIO KUNNA DADA AO POMOSE DUDU AO FI EPO TAGBA YEN PO AO GBODO FI OMI POO000000 AO KO OSE NA SINU IKE FUNFUN OLOMORI KAN, EPO TOSEKU YEN AO DA SINU IKE MIRAN, LILORE AO MA FI OSE YIII WE LALE ATI LARO TIA BA WE TAN AO MA FI EPO TINU IKE YEN PA IDODO WA, GBOGBO OTA TOBA NDI WA LOWO NI YIO KU IKU GBONA OOO OGUN YIII DAJU GIDI MOTI DANWO DADA

(14)
OGUN ARINANKORE

A'o wa Alakan eti Odo Kan, Ori Ologbo duudu Kan, Ori Ofafa Kan pelu Ere Oju-Omi, Irun Ori Afın di'e pelu Ori-Aluko ati Agbe pelu Oka Elelo Ibile pelu Pefumu.

•SISE RE•

A'o jo gbogbo re papo mon Oka Elelo Ibile a'o lo ti yo kun na daadaa, a'o gun ebu to po di'e mon Ose-Dudu Original, Iyoku Ebu to'ku a'o da sinu Pefumu.
Oka Elelo yen a'o ma ti'bowo Wa.
A'o mon we Ose Yi ti a'ban ti'n jade lo sibi'kan laro Kutu-Kutu, a'o si fın Pefumu Yi Saara.

•ASEJE RE•.

A'o gbe Ikoko ka na, a'o lo bu Omi Odo tin san'Lo, a'o da sinu Ikoko na, a'o re Ewe Olaa daadaa pelu Ewe Tanapowo sinu Re, A'o lo ra Edo Monlu a'o ge si Mesan, a'o da si Ori Ina, a'o fi Epo Pupa si, Iyo Si.
Ti'o ba ti jina tan ao su Osuka sile, a'o gbe Ikoko na si Ori Osuka yen. Idi Ikoko na ko gbodo kan Ile,

a'o ra Oti Schinapp ti a'ban je lowo a'o gbudo ba enikeeni so Oro kan-kan.
Ti a'ban ti'n je Ekiri kan a'o mon mu Oti yen le titi ti a'o fi je Aseje na tan, a'o wa lo fo Ikoko na mon'le.
O'PARI!!!

(15)

ELEYINI ISORA TI OWO ARAIYE KONI LE KA ENIYAN TODAJU
Ao fi iyere osun te ifa obaraka si ori ada, ao daa iyere osun sori Ada, ao waa teni ifa Obaraka, ao waa pe gbolohun si bayi.

GBÓLÓHÙN RE
Awon irin ni won nduro kogikogi, awon ajanaku lo fese mejeji rinle gbinrinmun gbinrinmun, awon lodifa fun obaraka, eniti apa araiye kole ka, eniti apa ara orun kole ka, eniti won lele ti won kole baa, obaraka eniti a baa ti a ko lefi se nkankan, oso ile, aje ile, babalawo, oni segun, pastor, woli to baa nperi emi lagbaja omo lagbaja nibi, ki ipa won maa kami, ki won maa se ara won Adua.

Ao da sinu eko gbigbona ao po po ao gbemun

(16)

IFA_OBARAKA_AGBELEPOTA_TOYANJU

Eo fi iyeru osu te ifa obaraka
Ao wa po ogi gbigbona sile eyi tale mutan ni ooo
Ao da ifa yiii si eko naa leyin tape ohun ree sibe

tan
Ao wa fi owo ro eko naa po ao ma fi owo(hand) mu eko naa

Ofore-:

Kosogun nile yimo kiki ote loku
Adifa fun awon eleye lojo tiwon
Npa lobaloba lojo ti won npa lojqloja
Ifa niki won ma lo awon eleye ko
Won o gbo ifa ni kiwon malo
Awom eleye ni ti awon koba lo
Nko?
Orunmila ni won yoo ma ri ogun akufa
Awon eleye gbera won gba oke odo
Woba obara ati ika nibi
Tiwon ti nfi omigbigbona wa eko gbona
Mu
Se awon komope eniti apa
Koka lanpe ni obara ika
Ki awon eleye wa ko gbogbo aburu
Ogun airana
Ogun airilo kuro ninu aye emi
L_l kuro lati onilo
Bi won bako tiwon ko bagba ki won bere
Sini rogun akufa larin arawọn
nbe

(17)
AROBI AJESARA IFA OBARAKA

Epo eyin adiye ibile tio pa funrare, ipepe irin agbede, odidi atare kan, ao jo papo, ao lo kunna dada, ao ro sinu ado ato tia bati felo, ao te die tabu yen ni ifa obaraka si, ao pe ohun re si•••••••

Ofore:Omalaro 3*, ika omesi 3*, olupona Ajakaye ayanue wole 3*, aji foruwolu 3*, eyin

ti e de oritameta epade orunmila ni nibo ni ehun lo, eni eun lo si ile aye oni tebade ile aye kini efe malose eni efe malo bati awon eniyan je orunmila ni ile aye tie loyi awon omo tohun lo po nibe, eni to bati ma oruko yin tosi mo ewo yin, eyin koni fowo kan, orunmila ni kini oruko yin, ki sini ewo yin? Eni ki orunmila wa epo eyin adiye, kosi wa ipepe irin agbede, omalaro lorun tanpe iwo ebo, toba sepe iwo ebo ni wonba ransi emi lagbaja omo lagbaja pe kin marojutu ile ayemi, obaraka o! bami kabi won kuro, kio dapada si awon tio ran wa, ika omesi loruko ti anpe ogun dudu inu ado, to ba jewipe iwo ogun dudu inu ado ni won ran si emi L omo L pe kin maa rujutu ayemi. Obaraka oo! Kabi naa kuro larami ko dapa losi odo eni to ran owa, Olupon Ajakaye ni orun ko ti anpe iwo soponan ni won ba ransi emi lagbaja omo lagbaja tio jeun rujutu aye mi, obaraka ooo! Kabi naa kuro larami, kio da pada sori eni tio ran e nise si emi lagbaja omo lagbaja, Ayanu e wole loruko ti anpe iwo epe ati ase, to ba sepe iwo epe ati ase ni won baransi emi lagbaja omo lagbaja kin marojutu ile aye mi obaraka oooo! Bami kabi naa kuro lara emi lagbaja omo lagbaja kiun ri ojutu ayemi, kio wa dabi padasi odo eni to ran o wa, ajiforuwolu lorunko ti anpe eyin iyami aje toba sepe eyin aje ni won ba ransi emi lagbaja omo lagbaja kin maa rojutu ile ayemi, obaraka ooooo! Kabi naa kuro lara mi ko dapada si odo eni to ran yin wa, tori moti maa oruko yin, mosi maa ewo yin, ibi oso, ibi aje, ibi elebo logun, ibi alfa, ibi woli ati bebelo obaraka ooo, kabi naa kuro lara mi ko dapada losi odo eni to ran o wa.. O daju Note inu igba lati fi foko mu.

(18)

Iṣẹ orijin tabi aforijin

Aso egun tó gbayii igi orijin osun akuko adie kán owu imule mejeji owo èyo mètá

Ao fì igi orijin ko arawon lè nu ao fì aso egun dì tì ko ni ri igi orijin na mon ao fì owu imule majeji dì tì áko nì ri aso n mó ao ta owo èyo na mó ao fì osun pá gbogbo árá ásírí yii ao pá adie na gba èjè rè sii ao saaa tì yio gbe toba gbe tán mmmmmmm. Ásírí nii oooo

Lilore ao fì ásírí yii sí árá wá ooo.

(19)
Oshole to tete gbera dada otun sise eyonu gbogbo aye

ISE todara pupo ni sugbon eni tiko ba ni imule agba Lara tele ko lese ise yii

Isena niyi
Odidi igbin nnla Kan
Eyele funfun Kan
Ewe ajeobale tutu
Epo OBO
Iyere osun
Ose Toba wuwa
Igba aje

Sisere
Aokoko gun igbin nnla Kuna dada aoko sibi Kan
Aogun ewe ajeobale ati epo OBO aowa da papo mo igbin tia tii gun yen
Aoda dash dash dash sori igbin tia tii gun yen
Aofi tee IFA oyeku meji

Aope gbolohun ree sii
Aowako ose le gbogbo ree Lori
Aotun gun papo morawon dada
Aofi eje eyele popapo
Aoge Ori eyele yen sibikan
Aowa laa aya eyele naa
Aogbe sinu igba aje aosi ayare soki ninu igba aje
Aowa ko oseyen le eyele naa Lori mole
Aoda iyere osun le Lori
Aotun tee IFA oyeku meji aope gbolohun ree sii bakana
Aowapo iyere osun yen pomo dada
Aowafi ori eyele yen gun Ori ose naa ninu igba aje
Aodepa fun ojo mesan 9days
Aomafi oseyen wee leyin ojo mesan after 9days you can start using it

Gbolohun ree
Kekere eleye ni nfi enu toso,irebe sise Niki je ki omode oroko idi agbon, odi IFA fun Orunmila lojo tio fin ba awon eleye sota,woni kini orunmila gbojule, orunmila nii Oso ile Kan kigboju koje igbin,aje ile kan kigboju koje epo OBO, orunmila nii agbalagba Kan kigboju koba Lori ewe ebiba,woni iwo orunmila awon yio mape sin orh nii,orunmila nii modi adaririkalu gbogbo eleye eyi tokere ewa sin mi gbogbo eleye owo money nnla nnla Niki eeh gbewa sin mi gbogbo eleye eyi tokere ewa sin mi ni origun mererin agbanla aye owo nnla nnla Niki eeh gbewa sin emi Lomo L lati eni loo

Awon akiyesi-pataki
Akogbodo nii ibalopo Kankan titi ojo mesan yen yio fipe
Akogbodo nii ibalopo nii ojo tiaba tiwe ose yii
Obinrin Toba she nnkan osu kogbodo fii owo Kan agbodo se etutu fún àwọn àgbà lati lo iṣẹ yii

(20)

EYONU NLA

Eyonu gidi bi ịṣẹ yi tosi dami loju dada,gbogbo eni ti oba gbiyanju re yio ri iyanu ore nla gba lati ọwọ awọn eniyan

Obi abata oloju 4 merin
orogbo nla 4
odidi ataare 4
eyin ibile ti o mo daada merin
atupa fitila oloju merindinlogun kan

Sise re:- aojo papo, ao loo ti yi o kunna daada, ao ro si inu igo funfun kan,

Lilo re:-ao maa to die die si inu inu fitila yi, ao maa ta ogere epo pupa si,ao maa la ni aaro kutu ki ato soro sí yan

(21)
ERO OFA SAKATU TABI ATA

Ewe enu opiye, Ose dudu ojulowo, kafura pelebe.

Ṣíṣe re: Ao lo ewe enu opiye yi pelu kafura pelebe papo, ao Fi ose ko, ao wa ra ose naa rodorodo, ao toju re si Inu Ike ti o ba gba Owo ti a ti le ma ri mu ni Koro kookan ti a ba Fe lo.

lilore:
Ao mu rogodo eyokan ninu ose yi, ao Fi sinu oti schnapp igo kan ao ma mu, ao si tun Fi oti naa

pa oju ofa naa.

NOTE: BI OSE BA SE PO TO NI KAFURA PELEBE TI AO LO YIO SE PO SI, FUN APEERE TI A BA FE LO OSE ONI #500 KAFURA PELEBE EYO MARUN PERE NI AO LO MO EWE YEN.

(22)
IBANTE KUTEKUTE TODAJU

Ibante ti en wo yiii ni agbara gidi gan 'bi ibante yen shey wa fun ara re ayeta ibon ni ibante yii je gan gan amo anfani wa fun eniyan lati di ogun eyikeyi mo lara pelu Emi na ni alase ati oludasile

Yara Atupa ogo
Slogan:Apa Ekute Ile Oka Awusa Enu gbirigbiri lomo

Eo wa ako alangba kan , owo eyo tikoluju mefa , ewe ewuro mewa (10) , eyo atare mewa (10) , owu dudu ati funfun...SISERE... Eo ran aso pupa ni ibante pelu okun re legbe osi ati otun Eo je ko tik daadaa kole ni ipon fun ibante yen Eo wa lo ja ewe ako ibepe oojo...NOTE... Eo ni jeki ewe yen kanle ti eba je ewe yen oooo Eo wa gbo ewe yen pelu omi Eo wa yo omi tegbo yen sibi kan Eo wa ju aso pupa teti ran ni ibante yen sinu omi yen pelu owo eyo mefa yen Eo fi sile sibe fun ojo meje lehin ojo keje Eo wa lo yo aso pupa yen ati owo eyo yen Eo sa sinu ike kofin gbe daadaa Eo budo sa sorun oooo koni sise ooooo Eo wa ran owo eyo yen mo aso yen meta ni apa otun meta ni apa osi owo eyo yen ma dabi star ni egbe otun ati osi yen Eo wa mu alangba Eo yo okan re ni tutu bahun Eo so alangba toku yen danu Eo wa mu ewe ewuro mewa yen Eo ma to le ara won pelu eyo atare mewa pere bayi ni Eo se to ewe kan eyo atare kan ewe kan eyo atare kan ewe kan

eyo atare kan bee ni Eo se ma to le ara won titi yio fi pe ewe ewuro mewa eyo atare mewa Eo wa fi okan alangba yen na le lori kehin pelu eyo atare ele kewa yen Eo wa gbe sinu etutu owu Eo dini ikobere pelu owu dudu ati funfun Eo wa di ikobere Eo wa ran ikobere yen mo ara ibante yen na odi lilo ooooooo...LILORE... Eo ma so ibante yen mo idi yin bi ose wa yen ohun sise ayeta ibon ..AKIYESI... Etun le ran ogun miran mo ara ibante yen toba wu yin

(23)

Ifá imule Olukesede

Musu Ehana (1), Ijapa nla (1), Igbin nla (1), Ewe ẹla topọ, Osun, Ikunmu osumare, Odidi atare kan, ao jo pọ, ao rọ sínu ṣẹẹrẹ, a pa Adiẹ Àkùkọ kan, a fi ẹjẹ rẹ ra ara ṣẹẹrẹ na, a fi iyẹ Adiẹ sí ara ṣẹẹrẹ yi, ao ma fi ogun yi f'ọkọ mu tabi Hot,

OHUN RẸ:-
Olukẹsẹde awo alase, orẹrẹ nkosun awo ogesa, Esu ile baba wọn ni kojẹ ki won ni Ẹni rere lara, Ifa jẹ kín ní ẹni rere lara, Orunmila jẹ kín ní eniyan atata lọdọ, ma jẹ ki oju ro ọmọ aráyé, ki wọn lè máa gbé owo nlánlá wà fún mi, nitori pe, oju ki ro Alabahun koto ro ọmọ rẹ l'asọ, oju ki ro Igbin kò tó wọ ọmọ rẹ l'ẹwu, Ẹfun loni ki ẹ wà fún mi ni owo nlánlá, Osun loni ki ẹ wa fi ohun rere sun mi bọ, Ifa moni òoto kín wá di olowo laye, Orunmila mo ni ooto kín wá di ọlọrọ láwùjọ nitori pe bi osumare ba pẹ koto yọ, ọmọ aráyé a bere rẹ, ẹ ma wa bere mi t'owo t'owo loni, Eji ogbè ooo(3x) iwọ ni ọba ifa, lọ gbe Olowo, Ọlọrọ...... É.t.c, wà fún mi loni t'owo t'owo ọwọ wọn, nitori bi Àkùkọ bakọ afi ọna han alejo, ẹ lọ juwe ile mi fún àwọn àlejò gidi, nitori ninu gbogbo igi to wa ni igbó ẹla ni kọkọ la, Emi ni kinla t'owo t'owo, kín lówó

lọwọ, t'ile t'ọna laafı jin Olọ́gbò, ẹ wa fı ohun rere jìn mí loni adua

(24)
IMULE AMINIYE

Aora eran aguntan kan toti bimari, Aopa aogba ejere sibi kan, aoge apa osire ni tutu tirun tirun arare, aofı eran iyoku se Sara,
Aotoju
Eku asin 16
Opolo gbigbe 16
Oga gbigbe 16
Ewe aluki lopolopo
Ewe ajeobale topo
Isu ogirisako totobi aogesi 16
Isu gbegbe 16
Epo obo lopolopo
Epo igi nla lopolopo
Aoge apa osi aguntan yi si 16
Aoko gbogbore sinu agbada ijogun tuntun, aoda eje aguntan ti apa Lee Lori, Aojopoaolokunna, aoda iyere osun topo die papo ma ogun ti ajoyi, aote ifa Osa meji si iwanba ti abafelo aope ofore si, aoro iyoku pama, sinu sere aofı omi po efun labelebe aofı Ra idi sere ti aroogun yi si ni idi aogbe sinu apo aso funfun

OFORE
Aminiye 3×
Afoniye 3×
Iya toboje 3×
Iya tobosun 3×
Iya ni sunkun 3×
Iya nisude 3×
Iya ominrinmirin niye 3×
Eyin mejeeje letele orunmila de otu ife lojosi, nigbati wande otu ife tan, Awan Ara ife ni iwoorunmila, Awan alejo re yi aoka ewo funwan,

orunmila Niki Wan ka ewo funwan, wanni kiAwan alejo orunmila kiwan oma kaila ejio, wanni kiwan omatu osun lorun, kiwan oma paarodede lekun, wanni kiwan omafi omo wewe otu ife se oweje, orunmila ni se gbogbo re niwangbo, wanni Awan gbo, orunmila wako apo apare olo iwere odo, igba tode ile Adan tan, niAwan baloka ila ejiwo, Awan aje batu osun lorun, wanpa arodede lekun, wanfi omo wewe ileife se aweje, ni Awan Ara otu ife balope orunmila, orunmila ni iwe odoni, orunmila bafa Idayo, Awan aje Niki orunmila omabinu, wanni oruko Awan Niki obere, ki Awan wa je o, ki asofun ooo, eni kini ni AMINIYE, enikeji ni Afoniye, eniketa ni iya toboje, enikerin ni iya tobosun, enikarun ni iyalosunkun, enikefa ni iya nisun ide, enikeje ni iya adunminrinmirin
niye, wanni ti orunmila batite ifa Osa eleye, ki ofi iyere osun te ifa re ki ofi eje aguntan Po, ki
oja ewe aluki si, ki otoju oka ego, wanni bi esu baje oko tobaje odan abowo fun aluki, eleye kankiigboju koje oka ego, enikan kiifi Opolo se aseje, AJE kan kiigboju koje eku asin, ajekankiigboju koje alagemo, modi ewe ajeobale loni, ajekan kogbodo jemi ma, AJE kan kiije obo, AJE
kiije igi nla, ki aje kan komale jemi ma, kiwan omale dimi lowo ire temi ma, Lori igbesi
AYEMI,
Aomafi fo Eko tutu mu ni ale,Aopo die ma ose ninu re aofi die ninu eje aguntan yi Po, aomafi we.

(25)IMULE AWON IYAMI TIN WON PE NI IMULE OSANPON GANRIGANRI

OPOLO GBIGBE KAN TABI TUTU EKU ASIN KAN OGA GBIGBE KAN EPO OBO EWE AFELORU ODIDI ATARE KAN AO JO PAPO AO LO BI ABATI FE LO IFA YI AO TENI OSA ELEIYE EPO PUPA LALALE OTIN SCHINAPU LARO

OFORE:OSANPON GANRI GANRI WON KOTAN INA, AJINJIN DUN DUN DUN AWON IGBO AWON NI WON SE IFA FUN ORUNMILA NI OJO BABA LOGBE AWON AJE PON WA SODE ISALU AIYE WONI BABA KOSOWA KALE ORUNMILA NI OUN KONI SOYIN KALE WONI TORI KINI ONITORI AWON OMO OUN NI WON TUN NI BABA SOWA KALE ORUNMILA NI OUN KONI SOWO KALE WON NI AWON YIO FUN ORUNMILA NI NKAN EWO AWON WONI KI ORUNMILA LO TOJU OPOLO KAN WONI OTONKULU WON KI PEJO JE OPOLO BI ABAMU OPOLO TI OJO KONKO AJU SILE NI ELO JU EMI L/L SILE ADUA WONI KIN ORUNMILA KOTU TOJU EKU ASIN WONI OUN EWO AWON NI FUN OSO AJE EMI L/L TIDI EWO LENU OSO ADUA WONI KOLOTOJU ALAGEMO TORI BI OLOKO BA DANA TAN KOGBODO SUN ALAGEMO JE Emi kekere omoyi ni ooo moki gbogbo eyin agbalagba imule tin mo muwa loni yi IMULE AWON IYAMI TIN WON PE NI IMULE OSANPON GANRIGANRI Emi kin rori ogun sugbon edanku egbinyanju re wo.OPOLO GBIGBE KAN TABI TUTU EKU ASIN KAN OGA GBIGBE KAN EPO OBO EWE AFELORU ODIDI ATARE KAN AO JO PAPO AO LO BI ABATI FE LO IFA YI AO TENI OSA ELEIYE EPO PUPA LALALE OTIN SCHINAPU LARO

OFORE:OSANPON GANRI GANRI WON KOTAN INA, AJINJIN DUN DUN DUN AWON IGBO AWON NI WON SE IFA FUN ORUNMILA NI OJO BABA LOGBE AWON AJE PON WA SODE ISALU AIYE WONI BABA KOSOWA KALE ORUNMILA NI OUN KONI SOYIN KALE WONI TORI KINI ONITORI AWON OMO OUN NI WON TUN NI BABA SOWA KALE ORUNMILA NI OUN KONI SOWO KALE WON NI AWON YIO FUN ORUNMILA NI NKAN EWO AWON WONI KI ORUNMILA LO TOJU OPOLO KAN WONI OTONKULU WON KI PEJO JE OPOLO BI ABAMU OPOLO TI OJO KONKO AJU SILE NI ELO

JU EMI L/L SILE ADUA WONI KIN ORUNMILA KOTU TOJU EKU ASIN WONI OUN EWO AWON NI FUN OSO AJE EMI L/L TIDI EWO LENU OSO WONI KOLOTOJU ALAGEMO TORI BI OLOKO BA DANA TAN KOGBODO SUN ALAGEMO JE EE

Ṣíṣe adura si